Ki irun ni iduro, ti oo ba wa ni ikapa, yaa ki i ni ijokoo, ti oo ba tun wa ni ikapa, ki i ni ifẹgbẹlelẹ

Lati ọdọ ‘Imrān ọmọ Husoyn – ki Ọlọhun yọnu si i– o sọ pe: Aisan jẹdíjẹdí mu mi, nigba naa ni mo wa bi Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – leere nipa irun, ni o wa sọ pe: «Ki irun ni iduro, ti oo ba wa ni ikapa, yaa ki i ni ijokoo, ti oo ba tun wa ni ikapa, ki i ni ifẹgbẹlelẹ».

[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe alaye wipe dajudaju ipilẹ ninu irun ni iduro, ayaafi ni igba ti ko ba si ikapa, nigba naa yio ki i ni ẹnití o jokoo, ti ko ba tun ni ikapa kiki irun ni ẹni ti o jokoo, o le ki i ni ifẹgbẹlelẹ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/10951